


**Láti ọwọ́ Ààrẹ Henry B. Eyring**
Olùdámọ̀ràn Ìkínní nínú Àjọ Ààrẹ Ìkínní

# Àwọn Ẹbí àti Àdúrà

Nígbàkan, bí mo ṣe jókó ní ẹ̀gbẹ́ bàbá mi ní gbogbo òru, ó sọ̀rọ̀ nípa ìgbà èwe rẹ̀. Ó sọ̀rọ̀ nípa ìfẹ́ àwọn òbí rẹ̀ ní àwọn ìgbà ìṣòro àti ti ìfẹ́ Bàbá rẹ̀ Ọ̀run àti Olùgbàlà. Mo mọ̀ pè àrùn jẹjẹrẹ ni ó nṣe ikú paá, nítorínáà kò yà mí lẹ́nu pé ní àwọn ìgbà míràn ó ńda àwọn ìmọ̀lára rẹ̀ fún Bàbá rẹ̀ Ọ̀run pọ̀ pẹ̀lú ìfẹ́ àti inúrere ti bàbá rẹ̀ ti ilẹ̀ ayé. Bàbá mi máa ńfi ìgbàkúgbà sọ pé nígbàtí òun bá gbàdúrà, òun lérò pé òun lè ri ẹ̀rín Bàbá Ọ̀run nínú òun.

Àwọn òbí rẹ̀ ti kọ́ ọ nípa àpẹrẹ láti gbàdúrà bíí pé ó nba Ọlọ́run sọ̀rọ̀ àti pé Ọlọ́run yíò dáa lóhùn nínú ìfẹ́. Ó nílò apẹrẹ náà títí dé òpin. Nígbàtí ìrora náà bá dé góngó, a ó ri ní ààrọ̀ lórí orókún rẹ̀ ní ẹ̀bá ibùsùn. Ó ti rẹ̀ẹ́ jù láti padà sí orí ibùsùn. Ó sọ fún wa pé òun ti ngbàdúrà láti bèèrè lọ́wọ́ Bàbá rẹ̀ Ọ̀run ìdí tí ó fi níláti jìyà púpọ̀ bẹ́ẹ̀ nígbàtí ó ti nfi ìgbàgbogbo tiraka láti jẹ́ ẹni rere. Ó sọ pé ìdáhùn dídára kan wá: "Ọlọ́run nílò àwọn ọmọkùnrin onígboyà."

Àti pé nítorínáà ó jagun lọ títí dé òpin, ní ìgbẹ́kẹ̀lé pé Ọlọ́run fẹ́ràn òun, ó fetísílẹ̀ sí òun, yíó sì gbé òun sókè. Ó jẹ́ alábùkún fún láti tètè mọ̀ àti láti máṣe gbàgbé pé Ọlọ́run olùfẹ́ kan wà ní itòsí bíi àdúrà.

Ìdí nìyí tí Olúwa fi kọ́ àwọn òbí pé, "Àti pé wọn yíò kọ́ àwọn ọmọ wọn bákannáà láti gbàdúrà, àti láti rìn ní ọ̀nà òtítọ́ níwájú Olúwa" (D&C 68:28).

A ti mú ìhìnrere ti Jésù Krístì padà bọ̀ sípò—pẹ̀lú Ìwé Mọ́rmọ́nì àti gbogbo kọ́kọ́rọ́ oyè-àlùfáà tí ó lè so àwọn ẹbí papọ̀—nítorí wípé Joseph Smith gẹ́gẹ́bí ọ̀dọ́mọkùnrin gbàdúrà nínú ìgbàgbọ́. Ó jẹ̀rè ìgbàgbọ́ náà nínú ẹbí olùfẹ́ ati olódodo.

Ogún ọdún sẹ́hìn Olúwa fún àwọn ẹbí ní ìmọ̀ràn yìí nínú "Ẹbí náà: Ìkéde kan sí Àgbáyé" láti ọwọ́ Àjọ Ààrẹ Ìkínní àti Iyejú Àwọn Àpọ́stélì Méjìlá: "Àwọn ẹbí àti àwọn ìgbeyàwó tí wọ́n yege ni a gbékalẹ̀ tí a sì nṣe ìtọ́jú wọn lórí ìpìlẹ̀ ẹ̀kọ́ ìgbàgbọ́, àdúrà, ìrònúpìwàdà, ìdáríjì, ọ̀wọ̀, ìfẹ́, àánú, iṣẹ́, àti àwọn eré ìdárayá tí ó péye."[1]

A jẹ gbèsè ìmoore kan tí kò ṣèe fi ojú rémọ́lẹ̀ sí ẹbí Wòlíì Joseph Smith fún títọ́-dàgbà rẹ̀. Ẹbí rẹ̀ fi àpẹrẹ hàn kìí ṣe nípa ìgbàgbọ́ àti àdúrà nìkan ṣùgbọ́n ìrònúpìwàdà, ìdáríjì, ọ̀wọ̀, ìfẹ́, àánú, iṣẹ́ ṣíṣe, àti àwọn eré ìdárayá tí ó péye bákannáà .

Àwọn ìran tí wọ́n wá lẹ́hìn yín lè pè yín ní alábùkún-fún nítorí àpẹrẹ àdúrà yín nínú ẹbí yín. Ẹ lè má gbé ìránṣẹ́ Ọlọ́run nlá kan dìde, ṣùgbọ́n nípa àwọn àdúrà yín àti pẹ̀lú àpẹrẹ òdodo yín ẹ lè ran Olúwa Jésù Krístì lọ́wọ́ láti gbé àwọn ọmọ ẹ̀hìn rere àti olùfẹ́ dìde.

Nínú gbogbo ohun tí ẹ lè yàn láti ṣe láti ran Olúwa lọ́wọ́, àdúrà yíò wà ní oókan àyà rẹ̀. Ó dàbí ẹnipé àwọn ènìyàn kan wà, nígbàtí wọ́n bá ngbàdúrà, wọ́n nmísí àwọn ẹlòmíràn láti la ojú wọn láti rí ẹni tí ó wà níbẹ̀. Ẹ lè di irú ẹni bẹ́ẹ̀.

Ẹ ronú nípa ohun tí èyínì lè túmọ̀ sí fún àwọn ẹnití wọ́n kúnlẹ̀ pẹ̀lú yín nínú àdúrà ẹbí. Nígbàtí wọ́n bá ní ìmọ̀lára pé ẹ̀ nbá Ọlọ́run sọ̀rọ̀ nínú ìgbàgbọ́, wọn yíò ní àlékún ìgbàgbọ́ láti sọ̀rọ̀ pẹ̀lú Ọlọ́run bákannáà. Nígbàtí ẹ bá gbàdúrà lati dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run fún àwọn ìbùkún tí

wọ́n mọ̀ pé ó ti wá, ìgbàgbọ́ wọn yíò gbèrú si pé Ọlọ́run ní ìfẹ́ wọn àti pé Ó ndáhùn àwọn àdúrà tìrẹ yíò sì dáhùn tiwọn. Èyínì lè ṣẹlẹ̀ nínú àdúrà ẹbí nìkan nígbàtí ẹ bá ti ni ìrírí náà nínú àdúrà ìkọ̀kọ̀, ní àsìkò sí àsìkò.

Mo ṣì njẹ́ alábùkún fún nípasẹ̀ bàbá àti ìyá kan tí wọ́n sọ̀rọ̀ pẹ̀lú Ọlọ́run. Àpẹrẹ wọn nípa agbára àdúrà nínú àwọn ẹbí ṣì nbùkún àwọn ìran tí wọ́n wá lẹ́hìn wọn.

Àwọn ọmọ àti àwọn ọmọ-ọmọ mi njẹ́ alábùkún lójojúmọ́ nípa àpẹrẹ ti àwọn obí mi. Ìgbàgbọ́ náà pé Ọlọ́run olùfẹ́ kan ngbọ́ tí ó sì ndáhùn àwọn àdúrà ni a ti fifún wọ́n. Ẹ lè ṣe irú ìjogún kan báyìí nínú ẹbí yín. Mo gbàdúrà pé ẹ ó ṣeé

**ÀWỌN ÀKỌSÍLẸ̀ RÁNPẸ́**

1. "Ẹbí náà: Ìkéde kan sí gbogbo Àgbáyé," *Liahona,* Nov. 2010, 129.

---

### ṢE AYẸYẸ OGÚN ỌDÚN TI ÌKÉDE LÓRÍ ẸBÍ

"Ẹbí náà: Ìkéde kan sí gbogbo Àgbáyé" kọ́ni ní àwọn ìpìlẹ̀ ẹ̀kọ́ tí ó kàn ṣe régí lóní gẹ́gẹ́bí ìgbàtí a kọ́kọ́ gbe kalẹ̀ ní ọjọ́ Kẹtàlélógún Oṣù Kẹ́sán, Ọdún 1995. Gbèrò pipe àkíyèsí àwọn ẹnìkọ̀ọ̀kan tàbí àwọn ẹbí tí ẹ̀ nkọ́ láti ṣe ayẹyẹ ogún ọdún ti ìkéde náà nípa:

1. Títo àwọn ìpìlẹ̀ ẹ̀kọ́ tí ó wà nínú rẹ̀ lẹ́sẹ-ẹsẹ tí ó ní àkànṣe pàtàkì fún wọn. (wò bí Ààrẹ Eyring ṣe nṣe èyí pẹ̀lú àdúrà nínú ọ̀rọ̀ tí ó wà lókè)
2. Ṣíṣe ìfikùnlukùn bí ìkọ̀ọ̀kan ìpìlẹ̀ ẹ̀kọ́ ṣe lè bùkún wọn lóní àti ní ọjọ́ iwájú.
3. Ṣíṣe àgbékalẹ̀ àwọn kókó ìyọrísí láti fi àwọn ìpìlẹ̀ ẹ̀kọ́ náà sínú ayé wọn àti láti ṣe àbápín wọn pẹ̀lú àwọn ẹlòmíràn.

## Ọ̀DỌ́

### Ṣíṣe iṣẹ́ lórí Àdúrà

Ààrẹ Eyring kọ́ni pé ẹbí yín lè gba ìbùkún nípa ìbáṣepọ̀ yín tí ò ní àgbára pẹ̀lú Bàbá Ọ̀run. Ẹ lè tún ìbáṣepọ̀ yín pẹ̀lú Rè ṣe nípa títún àdúrà yín ṣe! Ìwọ̀nyí ni àwọn èrò inú nípa bí a ṣe lè ṣe bẹ́ẹ̀:

Ṣíwájú kí ẹ tó bẹ̀rẹ̀ àdúrà yín, ẹ fi àsìkò díẹ̀ sílẹ̀ láti ronú nípa ohun tí ẹ fẹ́ sọ. Ẹ gbèrò àwọn ìbèèrè tí ẹ lè ní tàbí àwọn ohun tí ó ti ndàmú yín—àní ẹ tilẹ̀ lè kọ wọn sílẹ̀ kí ẹ má bàá gbàgbé. Lo àsìkò yí bákannáà láti mú ọkàn yín mọ́ kúrò ní ìrúkèrúdò ti ọjọ́ náà kí ẹ lè fojúsí ìmọ̀lọ́kàn jẹ́jẹ́ ti Ẹ̀mí Mímọ́. Bí ọkàn yín bá fẹ́ máa ṣáko kiri nígbàtí ẹ̀ ba ngbàdúrà, ẹ tiraka láti wòó bí Bàbá Ọ̀run ṣe nfetísílẹ̀. Sọ àwọn kókó. Bákannáà, fi àwọn ìṣẹ́jú díẹ̀ sílẹ̀ ní ìparí àdúrà náà láti fetísílẹ̀ sí àwọn ìṣílétí ti Ẹ̀mí. Ẹ lè kọ àwọn ìmọ̀lọ́kàn yín sílẹ̀ nínú ìwé àkọsílẹ̀ yín.

Rántí pé àdúrà jẹ́ irú iṣẹ́ kan, nítorínáà máṣe dàmú tí ó bá gba àṣetúnṣe tàbí tí ó dàbíí pé ó le! Ìgbìyànjú yín ní gbígba àdúrà lè ràn yín lọ́wọ́ láti ní ìbáṣepọ̀ kan pẹ̀lú Ọlọ́run tí yíò bùkún àwọn ìràn.

## ÀWỌN ỌMỌDÉ

### Olùránni-létí Àdúrà Kan

Ààrẹ Eyring kọ́ni pé ó ṣe pàtàkì láti gbàdúrà pẹ̀lú ẹbí yín. Ẹ lè jẹ́ àpẹrẹ kan sí ẹbí yín nípa gbígba àdúrà lójoojúmọ́. Ẹ lè rán ẹbí yín létí bákannáà láti gbàdúrà papọ̀ lójoojúmọ́. Rántí àtúnsọ yí láti inú ọ̀rọ̀ míràn láti ọwọ́ Ààrẹ Eyring: "Bàbá Ọ̀run ngbọ́ àwọn àdúrà yín. Ó fẹ́ràn yín. Ó mọ orúkọ yín" ("Ìfihàn Tí-ó-ntẹ̀síwájú," *Amọ̀nà,* Oṣù Kọkànlá. Ọdún 2014, 73). Ẹ kọ àtúnsọ yìí jáde sí orí káàdì kan tàbí ẹ̀là ìwé kí ẹ sì fi sí ibi tí gbogbo ẹbí yín ti lè ríi. Ní ọ̀nà yí ẹ lè máa rántí nígbàgbogbo pé Bàbá Ọ̀run nfẹ́ láti gbọ́ láti ẹnu yín!

© 2015 láti ọwọ́ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. Tí a tẹ̀ ní USA.
Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/15. Àṣẹ Ìyírọ̀padà: 6/15. Ìyírọ̀padà ti *First Presidency Message, September 2015.* Yoruba. 12589 779

# Ìṣe Àtọ̀runwá ti Jésù Krístì: Tí ó lágbára tí ó sì kún fún Ògo

*Fi tàdúrà tàdúrà ṣe àṣàrò ohun èlò yí kí o sì ṣe àwárí láti mọ ohun tí ìwọ yíò ṣe àbápín rẹ̀. Báwo ni níní òye ìṣe àtọ̀runwá ti Olùgbàlà ṣe nmú kí ìgbàgbọ́ rẹ nínú Rẹ̀ pọ̀ síi àti láti bùkún àwọn wọnnì tí ò nbojútó nípa ìbẹniwò kíkọ́ni? Fún ìwífúnni síi, lọ sí* ***reliefsociety.lds.org****.*

**Ìgbàgbọ́, Ẹbí, Ìrànlọ́wọ́**

*Èyí ni apákan ti onírúurú àwọn Ọ̀rọ̀ Ìbẹ̀niwò Kíkọ́ni tí ó ńfi àwọn ìṣe àtọ̀runwá ti Olùgbàlà hàn.*

Àwọn ìwé mímọ́ kọ́ wa pé Jésù Krístì "gba gbogbo agbara, ní ọ̀run àti ní ilẹ̀ ayé, àti pé ògo ti Bàbá wà pẹ̀lú rẹ̀" (D&C 93:17). Alàgbà M. Russell Ballard ti Iyejú Àwọn Àpóstélì Méjìlá sọ pé nípa agbára yí ni Olùgbàlà wa dá àwọn ọ̀run àti ilẹ̀ ayé, ṣe àwọn iṣẹ́ ìyanu, tí ó sì fi ara da ìrora Gẹ́tsémánì àti Kálfárì. [1] Bí a ṣe wá láti ní óye èyí, ìgbàgbọ́ wa nínú Krístì yíò pọ̀ si, a ó sì lágbára si.

Bí a ṣe ndá tí a sì npa àwọn májẹ̀mú tẹ́mpìlì mọ́, Olúwa nbùkún wa pẹ̀lú agbára rẹ̀. Linda K. Burton, ààrẹ gbogboògbò Ẹgbẹ́ Ìrànlọ́wọ́, sọ pé: "Pípa májẹ̀mú mọ́ nfúnni lókun, nfúnni lágbára, ó sì ńdáààbo bò. . . . Mo pàdé ọ̀rẹ́ tuntun olùfẹ́ kan láìpẹ́. Ó jẹ́rí pé lẹ́hìn tí òun ti gba ìfi-ẹ̀bùn-wọni ti tẹ́mpìlì, ó ní ìmọ̀lára okun pẹ̀lú agbára láti tako àwọn àdánwò." [2]

Nífáì ṣe ìjẹ́rí sí agbára májẹ̀mú: "Èmi, Nífáì, kíyèsí agbára Ọ̀dọ́ àgùtàn Ọlọ́run, tí ó sọ̀kalẹ̀ . . . lé orí àwọn ènìyàn májẹ̀mú ti Olúwa, . . . wọ́n sì gbáradì pẹ̀lú òdodo àti pẹ̀lú agbára Ọlọ́run nínú ògo ńlá" (1 Nífáì 14:14).

## Àwọn Ìwé Mímọ́ ní Àfikún

Jeremíàh 51:15; Ìfihàn 1:6; Jákọ́bù 4:6–7; Mòsíàh 3:17

## Láti inú àwọn Ìwé Mímọ́

Ní kíkún-fún àánú nlá sí Martha àti Màríà, Jésù Krístì gbé arákùnrin wọn Lásárù dìde kúrò ní ipò òkú nípa agbára Ọlọ́run tí Òun ní.

Jésù dé ilé Martha àti Màríà lẹ́hìn tí Lásárù ti wà nínú ibojì fún ọjọ́ mẹ́rin. Wọ́n lọ sí orórì Lásárù, Jésù sì pàṣẹ pé kí wọ́n gbé òkúta tí ó bo ẹnu ọ̀nà náà kúrò. Jésù sọ fún Martha, "Èmi kò ti wí fún ọ, pé, bí ìwọ bá gbàgbọ́, ìwọ yíò rí ògo Ọlọ́run?" Nígbànáà ó gbàdúrà sí Ọlọ́run Bàbá ó sì "kígbe lóhun rara pé, Lásárù, jáde wá.

"Ẹnití ó kú náà sì jáde wá, tí a fi aṣọ òkú dì tọwọ́ tẹsẹ̀." (Wo Jòhánù 11:1–45.) Olùgbàlà lo agbára Rẹ̀ láti rà wá padà àti láti ró wa ní agbára. Ìgbàgbọ́ wa nínú Rẹ̀ yíò pọ̀ síi bí a ṣe nrántí pé Ó kún fún agbára àti ògo.

**ÀWỌN ÀKỌSÍLẸ̀ RÁNPẸ́**

1. Wo M. Russell Ballard, "Èyí ni Iṣẹ́ Mi àti Ògo Mi," *Atọ́nà,* Oṣù Kárún, Ọdún 2013, 18.
2. Linda K. Burton, "Agbára náà, Ayọ̀, àti Ìfẹ́ ti Pípa Májẹ̀mú Mọ́,"*Atọ́nà,* Oṣù Kọkànlá. Ọdún 2013, 111.

### *Gbèrò Èyí*

Báwo ni agbára Ọlọ́run ṣe nró wá pẹ̀lú àgbára àti ògo?

© 2015 láti ọwọ́ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. Tí a tẹ̀ ní USA. Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/15. Àṣẹ Ìyírọ̀padà: 6/15. Ìyírọ̀padà ti *Visiting Teaching Message, September 2015.* Yoruba. 12589 779